Láti Ọwọ́ Àárẹ Thomas S. Monson

Ìgbọ̀ràn ń mú àwọn Ìbùkún wá

Ìmọ̀ ti òtítọ́ àti àwọn ìdáhùn sí àwọn ìbéèrè wa nlá jùlọ máa ń wá sí ọ̀dọ̀ wa bí a bá ṣe gbọ́ràn sí àwọn àṣẹ Ọlọ́run.

È yin arákùnrin àti arábìnrin mi olùfẹ́, ọpẹ́ mi ti pọ̀ tó lati wà pẹ̀lú yín ní òwúrọ̀ yí. Mo tọrọ fún ìgbàgbọ́ àti àwọn àdúrà yín bí mo ṣe nfẹ̀sì sí ànfàní láti báa yín sọ̀rọ̀.

Ní gbogbo àwọn ọjọ́, àwọn ọkùnrin àti obìnrin ti ń wá ìmọ̀ àti òye kiri nípa ìwàláyé ikú yìí àti ipò wọn àti èrèdí wọn nínú rẹ̀, àti bákannáà fún ọ̀nà sí àláfíà àti ìdùnnú. Olukúlùkù wa nṣe irú ìwákiri bẹ́ẹ̀.

Ìmọ̀ àti òye yìí wà ní àrọ́wọ́tó gbogbo ènìyàn. Wọ́n wà nínú àwọn òtítọ́ tí ó jẹ́ ti ayérayé. Nínú Ẹ̀kọ́ àti Àwọn Májẹ̀mú, ìpín kíní, ẹsẹ̀ kọkàndínlógójì, a kà: "Kíyèsíi, àti wòó, Olúwa ni Ọlọ́run, àti pé ẹ̀mí ṣe ìjẹ́rí, àti pé ẹ̀rí náà jẹ́ òtítọ́, àti pé òtítọ́ dúró láéláé àtí láé."

Akéwì kan kọ:

Bí àwọn ọ̀run tilẹ̀ sálọ àti tí àwọn orísun omi ayé fọ́,
Òtítọ́, àkópọ̀ ìwàláyé, yíó borí ohun tí ó lè burú jù,
Ayérayé, àìyípadà, títí láé.[1]

Àwọn kan yíó bèrè, "Níbo ni ó ti rí irú òtítọ́ bẹ́ẹ̀, àti báwo ni á o ṣe dá a mọ̀?" Nínú ìfihàn kan tí a fúnni nípasẹ̀ Wòlîì Joseph Smith ní Kirtland, Ohio, ní Oṣù Kárún ti Ọdún 1833, Olúwa kéde:

"Òtítọ́ ni ìmọ̀ àwọn nkan bí wọ́n ṣe wà, àti bí wọ́n ṣe ti wà rí, àti bí wọn yíó ṣe wá. . . .

"Ẹ̀mí ti òtítọ́ jẹ́ ti Ọlọ́run. . . .

"Àti pé kò sí ẹnití yíó gba ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àfí tí ó bá pa àwọn àṣẹ rẹ̀ mọ́.

"Ẹnití ó bá pa àwọn àṣẹ [Ọlọ́run] mọ́ gba òtítọ́ àti ìmọ́lẹ̀, títí di ìgbà tí yíó di ológo ninú òtítọ́ tí ó sì mọ ohun gbogbo."[2]

Irú ìlérí ológo wo ni èyí! "Ẹnití ó bá pa àwọn àṣẹ [Ọlọ́run] mọ́ gba òtítọ́ àti ìmọ́lẹ̀, títí di ìgbà tí yíó di ológo ninú òtítọ́ tí ó sì mọ ohun gbogbo."

Kò sí ìwúlò fún ìwọ tàbí fún èmi, ní ayé ọ̀làjú yìí tí a ti ṣe àmúpadàsípò ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ ìhìnrere, láti wa ọkọ̀ ní àwọn òkun tí a kò í tîì dámọ̀ tàbí rìn ìrìn àjò ní àwọn ọ̀nà tí a kò sàmì sí láti wá òtítọ́. Bàbá Ọ̀run olóore tí ya ọ̀nà wa, Ó sì ti pèsè atọ́nisọ́nà tí kìí yẹ̀—àní *ìgbọ̀ràn*. Ìmọ̀ ti òtítọ́ àti àwọn ìdáhùn sí àwọn ìbéèrè wa tí ó tóbi jùlọ ńwá sí ọ̀dọ̀ wa bí a bá ṣe ngbọ́ràn sí àwọn àṣẹ Ọlọ́run.

À ń kọ́ ìgbọ̀ràn ní gbogbo ìgbé ayé wa. Bẹ̀rẹ̀ láti ìgbà tí a kéré gan, àwọn tí wọ́n ní ojúṣe fún ìtọ́jú wa ṣe àgbékalẹ̀ àwọn ìtọ́sọ́nà àti àwọn òfin láti ṣe ìdánilojú ààbò wa. Ayé yíó rọrùn fún gbogbo wa tí a bá lè gbọ́ràn sí irú òfin bẹ́ẹ̀ pátápátá. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ wa, síbẹ̀síbẹ̀, n kẹ́kọ́ nípa ìrírí tí ọgbọ́n ti jíjẹ́ olùgbọ́ràn.

Nígbà tí mó ndàgbà, ní olúkúlùkù ìgbà oòrùn láti ìbẹ̀rẹ̀ Oṣù kéje títí di ìbẹ̀rẹ̀ Oṣù kẹ́sán, àwọn ìdílé mi gbé ní ilé inú oko ní Vivian Park ní Ògbùn Provo ní Utah.

Ìkan nínú àwọn òrẹ́ mi tímọ́tímọ́ nígbà àwọn ọjọ́ àìbìkítà wọ̀nnì nínú ọgbùn nã ni Danny Larsen, tí ìdílé tirẹ̀ náà ní ilé nínú oko kan ní Vivian Park. Lójojúmọ́ òun àti èmí ń jẹ́ káàkiri párádísè ọmọkùnrin yìí, à máa npa ẹja nínú odò ṣíṣàn àti odò nla, à máa nṣa òkúta àti àwọn ìṣura míràn, ní ríríìn, ní gígùn òkè, àti ní gbígbádùn olúkúlùkù ìṣẹ́jú ti olúkúlùkù wákàtí ti olúkúlùkù ọjọ́.

Ní òwúrọ̀ kan, Danny àti èmi pinnu pé a fẹ́ ní iná-àgọ́ ní ìrọ̀lẹ́ nã pẹ̀lú gbogbo àwọn òrẹ́ wa nínú ọgbun. A kàn nílò láti palẹ̀mọ́ agbègbè kan ní pápá kan tí ó súnmọ́ níbi tí gbogbo wa lè péjọ sí. Koríko ìgbà Oṣù kẹ́fà ti bo gbogbo pápá náà wọ́n sì ti gbẹ wọ́n sì ní ẹ̀gún , èyí tí ó mú kí pápá náà ṣe àìwúlò fún èrò wa. A bẹ̀rẹ̀ láti má a fa àwọn koríko gíga náà ní ìpinnu láti palẹ̀mọ́ agbègbè nlá

róbótó kan. A fà a sì ja a pẹ̀lú gbogbo ipá wa, ṣùgbọ́n gbogbo ohun tí a lè rí kò ju àwọn ẹ̀kúnwọ́ àwọn èpo líle nã lọ. A mọ wípé iṣẹ́ yìí yíó gba gbogbo ọjọ́, àti pé okun-inú àti ìyá gágá ara wa ti ń díkù.

Àti nígbànáà ohun tí mo rò wípé ó jẹ́ àbáyọ pípé wá sínú ọkàn ọmọ-ọdún-méjọ mi. Mo wí fún Danny, "Ohun tí a kàn nílò láti ṣe ni kí a dáná sun àwọn èpo yìí. À ó kàn *jó* ibi róbótó kan nínú àwọn èpo náà!" Lọ́gán ni ó gbà, mo sì sáré lọ sí ilé inú oko wa láti mú àwọn ìṣáná díẹ̀.

Kí a máṣe rí ẹnikẹ́ni yín tí ó rò wípé ní ọmọ ọdún méjọ jẹ́jẹ́, a ní ìyọ̀nda láti lo ìṣáná, mo fẹ́ fi yé e yín dájú pé a ti kà á ní èèwọ̀ fún Danny àti èmi láti lò wọ́n láì sí àbojútó àgbàlagbà. A ti kìlọ̀ léraléra fún àwa méjìjì nípa àwọn ewu iná. Síbẹ̀síbẹ̀, mo mọ ibi tí àwọn ìdílé mi fi ìṣáná pamọ́ sí, àti pé a nílò láti palẹ̀mọ́ pápá nã. Láì tilẹ̀ ronú si lẹ́ẹ̀mejì, mo sáré lọ sí ilé inú oko wa, mo sì mú igi ìṣáná díẹ̀, ní ríríi dájú pé kò sí ẹnìkankan tí ó ńwò mí. Mo tètè fi wọ́n pamọ́ sínú ìkan nínú àwọn àpò mi.

Mo sáré padà sọ́dọ̀ Danny , ní ìrúsóké pé nínú àpò mi, mo ní àbáyọ sí wàhálà wa. Mo rántí ìronú mi pé ina náà yíó kàn jó dé ibi tí a fẹ́ àti lẹ́hìnnáà yíó kàn pa ara rẹ̀ bĩ idán.

Mo ṣá ìṣáná kan lórí òkúta mo sì dáná sí koríko ìgbà Oṣù kẹ́fà gbígbẹ náà. Ó gbiná bí ẹnipé a ti rìí sínú epo pẹtirólù. Lákọ́kọ́, ìnú Danny àti èmi ndùn bí a ṣé nwò àwọn èpo náà tí ó npoorá, ṣùgbọ́n láìpẹ́ ó hàn kedere pé iná náà kò ṣetán láti kú fún ara rẹ̀. A jáyà nígbà tí a ṣe àkíyèsí pé kò sí ohun tí a lè ṣe láti dáa dúró. Àwọn ọwọ́ iná ìlẹ́ru náà bẹ̀rẹ̀ sí tẹ̀lé koríko líle náà gun òkè gba ẹ̀gbẹ́ orí òkè, wọ́n sì ń ṣe àkóbá fún àwọn igi pine àti ohun gbogbo tí ó kù ní ọ̀nà rẹ̀.

Níkẹhìn, a kò ní ìyàn kankan ju kí a sáré lọ fún ìrànlọ́wọ́. Láìpẹ́, gbogbo àwọn arákùnrin àti arábìnrin tí ó wà ní àrọ́wọ́tọ́ ní Vivian park ń sáré lọ sábọ̀ pẹ̀lú àwọn àpò Burlap tutu, tí wọ́n sì nlu àwọn ọwọ́ iná náà ní ìyànjú láti pa wọ́n. Lẹ́hìn wákàtí díẹ̀, àwọn ẹ̀gẹ́ iná tí ó kù di pípa. A ti gba àwọn igi ọlọ́jọ́ pípẹ́ pine náà là, àti àwọn ilé tí àwọn ọwọ́ iná náà kò bá ti dé níkẹhìn.

Danny àti èmí kọ́ àwọn ẹ̀kọ́ líle ṣùgbọ́n pàtàkì ní ọjọ́ náà—kókó rẹ̀ tí ó jẹ́ pàtàkì ti ìgbọràn.

Àwọn àkóso àti àwọn òfin wà láti ṣè ìrànlọ́wọ́ fún àrídájú àbò ti ara wa. Bákannáà, Olúwa ti pèsè àwọn ìtọ́ṣọ́nà àti àwọn àṣẹ láti ṣè ìrànlọ́wọ́ fún àrídájú àbò ti ẹ̀mí wa kí a ba lè yege nínú ìrin ìgbé ayé tí ara ikú alárékérekè yí kí a sì padà níkẹhìn sí ọ̀dọ̀ Bàbá Ọ̀run.

Ní ọgọ́rún ọdún sẹ́hìn, sí àwọn ìran kan tí wọ́n jínlẹ̀ nínú òfin àtọwọ́dọ́wọ́ ti ìrúbọ ẹranko, Sámúẹ́lì fí ìgbóyà kéde: "Ìgbọràn sàn ju ẹbọ lọ, ìfetísílẹ̀ sì sàn ju ọ̀rá àgbò lọ."[3]

Ní ìgbà yìí, Olúwa fi han Wòlîi Joseph Smith pé Òun nílò "ọkàn àti ẹ̀mí tí ó yọ̀nda; àti ẹni tí ó yọ̀nda tí ó sì gbọ́ràn yíó jẹ ire ti ilẹ̀ Síónì ní àwọn ọjọ́ ìkẹhìn yìí."[4]

Gbogbo àwọn wòlîi, ti àtijọ́ àti ti ìgbàlódé, ti mọ̀ wípé ìgbọràn jẹ́ kòṣeémání fún ìgbàla wa. Nífâì kéde, "Èmi yíò lọ láti ṣe àwọn ohun tí Olúwa ti pa láṣẹ."[5] Bí àwọn míràn tilẹ̀ kọsẹ̀ nínú ìgbàgbọ́ àti ìgbọràn wọn, Nífâì kò fi ìgbà kan kùnà láé láti ṣe ohun tí Olúwa bèrè lọ́wọ́ rẹ̀. Àwọn ìran tí a kò lè sọ ti di alábùkún ní ẹ̀san rẹ̀.

ìgbọràn kan tí nfúnni ní ìmísí ìjìnlẹ̀ ọkàn niti Abrahamu àti Isaaki. Àkọsílẹ̀ kan nípa ìgbọràn ti ó ní ìmísí ìjìnlẹ̀ sí ọkàn ni ti Abrahamu àti Isaaki. Ó ti má a jẹ́ ìrora líle tó fún Abrahamu, ní ìgbọràn sí àṣẹ Ọlọ́run, láti mú àyànfẹ́ rẹ̀ Isaakì lọ sí ilẹ̀ Moria láti fi ṣe ìrúbọ. Njẹ́ a lè wòye bí ọkàn Abrahamu ṣe wúwo tó bí ó ṣe rìn ìrìnàjò lọ sí ibi yíyàn náà? Dájúdájú, àròkàn gbọ́dọ̀ ti run ara rẹ̀ kí ó sì fi ìyà jẹ ọkàn rẹ̀ bí ó ṣe de Isaaki, gbé e sí órí pẹpẹ, tí ó sì mú ọbẹ láti pa á. Pẹ̀lú ìgbàgbọ́ àìṣiyèméjì àti ìgbẹ́kẹ̀lé tó péye nínú Olúwa, ó jẹ́ ìpè sí àṣẹ Olúwa. Báwo ni àsọsíta nã ti ní ógo tó, àti pẹ̀lú irú ìkíni káàbọ̀ ìyanu wo ní ó wá: "Maṣe fọwọ́kan ọmọdé ni, bẹ́ẹ̀ni ìwọ kò gbọdọ̀ ṣe é ní nkan: nítorí nísisìnyí èmí mọ̀ pé ìwọ́ bẹ̀rù Ọlọ́run, nígbàtí ìwọ kò ti dùnmí ní ọmọ rẹ, ọmọ rẹ náà kanṣoṣo."[6]

A ti pe Abrahamu lẹ́jọ́ a sì ti dán an wò, àti fún ìgbàgbọ́ àti ìgbọràn rẹ̀, Olúwa fún un ní ìlérí ológo kan: "Nínú irú-ọmọ rẹ ní a ó bùkún fún gbogbo orílẹ̀-èdè ayé: nítorí tí ìwọ́ ti gba ohùn mi gbọ́."[7]

Bíótilẹ̀jẹ́pé a kò ní kí a dán ìgbọràn wa wò ní irú ọ̀nà onídárayá tí ó nrin ni lọ́kan bẹ́ ẹ̀, a nílò ìgbàgbọ́ lọ́wọ́ wa bákan náà.

Àárẹ Joseph F. Smith kéde ní Oṣù kẹ́wa Ọdún 1873, "Ìgbọràn ní òfin kíní ní ọ̀run."[8]

Aárẹ Gordon B. Hinckley wípé, "Ìdúnnú ti àwọn ènìyàn mímọ́ ti ọjọ́ ìkẹhìn, àláfíà ti àwọn ènìyàn mímọ́ ti ọjọ́ ìkẹhìn, ìtẹ̀síwájú ti àwọn ènìyàn mímọ́ ti ọjọ́ ìkẹhìn, ìṣoríire ti àwọn ènìyàn mímọ́ ti ọjọ́ ìkẹhìn, àti ìgbàlà àti ìgbéga ológo jùlọ ayérayé ti àwọn ènìyàn wọ̀nyí dá lé ríríìn nínú ìgbọràn sí àwọn ìmọ̀ràn ti . . .Ọlọ́run."[9]

Ìgbọràn ni àmì ìdánimọ̀ àwọn wòlîi; Ó ti pèsè okun àti ìmọ̀ fún wọn ní gbogbo ọjọ́. Ó ṣe kókó fún wa kí a kíyèsí pé àwa, bákannáà, ní ẹ̀tọ́ sí orísun okun àti ìmọ̀ yí. Ó wà lọ́gan ní àrọ́wọ́tó olúkúlùkù wa bí a bá ṣe gbọ́ràn sí àwọn àṣẹ Ọlọ́run.

Jákèjádò àwọn ọdún, mo ti mọ àìmoye ènìyàn tí wọ́n ti jẹ́ olódodo tí wọ́n sì gbọ́ràn. Mo ti jẹ́ alábùkún fún mo sì ní ìmísí nípa wọn. Njẹ́ kí nṣe alábápín ìtàn ìrú ènìyàn méjì bẹ́ẹ̀ pẹ̀lú yín.

Walter Krause jẹ́ ọmọ Ìjọ tí ó dúró ṣinṣin tí, pẹ̀lú mọ̀lẹ́bí rẹ̀, ó gbé ní ohun tí a wá mọ̀ bíi Germany ti Ìla Oòrun lẹ́hìn Ogun Àgbáyé Kejì. Láì ka àwọn ìṣòro tí ó dojúkọ sí nítorí àìsí òmìnira ní apá ayé náà ní ìgbà náà, Arákùnrin Krause jẹ́ ọkùnrin kan tí ó fẹ́ràn tí ó sì sin Olúwa. Ó ṣe àmúṣẹ gbogbo ojúṣe tí wọ́n fún pẹ̀lú ìgbágbọ́ àti ẹ̀rí ọkàn.

Arákùnrin kejì, Johann Denndorfer, ọmọ ìlú Hungary, di ayípadà sí Ìjọ ní Germany, ó sì ṣe ìrìbọmi níbẹ̀ ní Ọdún 1911 ní ọmọ ọdún métadínlógún. Kò pẹ́ léhìn náà, ó padà sí Hungary. Lẹ́hìn Ogun Àgbáyé Kejì, ó di ẹlẹ́wọ̀n ní ìlú ara rẹ̀, ní ìlú Debrecen. A ti gba òmìnira bákan náà lọ́wọ́ àwọn ènìyàn Hungary.

Arákùnrin Walter Krause, tí kò mọ Arákùnrin Denndorfer, gba ojúṣe láti jẹ́ olùkọ́ni ilé rẹ̀ àti láti bẹ̀ẹ́wò lóòrèkóòrè. Arákùnrin Krause pe ẹnìkejì olùkọ́ni ilé rẹ̀ ó sì wí fún un: "A ti gba ojúṣe láti bẹ Arákùnrin Johann Denndorfer wò. Sé o ó wà ní àrọ́wọ́tọ́ láti lọ pẹ̀lú mi ní ọ́sẹ̀ yí láti rí i kí a sì fún un ní iṣẹ́ ìhìnrere kan?" Àti nígbànáà, ó ṣe àfikún, "Arákùnrin Denndorfer n gbé ní Hungary."

Ẹnìkejì rẹ̀ tí ẹ̀rù báà bèrè, "Nígbà wo ní a ó kúrò?"

"Òla," ní ìdáhùn tí ó wá láti ọ̀dọ̀ Arákùnrin Krause.

"Nígbà wo ní a ó padà sílé?" ẹníkejì rẹ̀ bèrè.

Arákùnrin Krause da lóhùn, "A, ní bí ọ̀sẹ̀ kan – tí a *bá* padà."

Àwọn alájọrìn olúkọ́ni ilé méjèjì lọ láti bẹ Arákùnrin Denndorfer wò, ní ìrìnàjò nípa ọkọ̀ ojú irin àti ọkọ̀ ojú ọ̀nà láti agbègbè ìha àriwá mọ́ ìla òòrun ti Germany sí Debrecen, Hungary – ìrin nlá gidi. Arákùnrin Denndorfer kò ní àwọn olùkọ́ni ilé láti ṣìwájú ogun. Nísisìyí, nígbà tí ó rí àwọn ìránṣẹ́ Olúwa yìí, ó kún fún ìmoore pé wọ́n wá. Lákọ́kọ́, ó kò láti bọwọ́ pẹ̀lú wọn. Dípò, ó lọ sí iyàrá rẹ̀ ó sì mú àpótí tí ó ní ìdámẹ́wá rẹ̀ nínú, tí ó ti dájọ́ fún ọdún díẹ̀. Ó na ìdámẹ́wá rẹ̀ sí àwọn olùkọ́ní ilé rẹ̀ ó sì wípé, "Nísisìyí, mo wà ní ré̩gí pẹ̀lú Olúwa." *Nísisìyí* mo ní ìmọ̀lára jíjẹ́ yíyẹ láti bọ ọwọ́ àwọn ìránṣẹ́ Olúwa!" Arákùnrin Krause sọ fún mi lẹ́hìn náà pé òun kò leè fi ọ̀rọ̀ júwe ìmọ̀-inú tí òhun ní láti rí i pé arákùnrin olóótọ́ yìí, tí kò ní ìfarakanra kankan pẹ̀lú Ìjọ fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún, ti yọ ìpín kẹ̀wá lára owo iṣẹ́ ṣíkíní rẹ̀ ní ìgbọràn àti ní dééédéé láti fi san ìdámẹ́wá rẹ̀. Ó ti fí pamọ́ lái mọ ìgbà tàbí bí yíó tilẹ̀ ní ànfàní láti san án.

Arákùnrin Walter Krause ṣe aláìsí ní ọ́dún mésán sẹ́hìn ní ẹni ọdún mẹ́rìnléláádọ́rin. Ó sìn ní ódodo àti ní ìgbọràn ní gbogbo ayé rẹ̀, ó sì jẹ́ ẹni ìmísi fún mi àti gbogbo àwọn tí ó mọ̀ ọ́. Nígbátí a bá ní kí ó ṣe awọn ojúṣe, kò jẹ́ ní ìbéèrè láé, kò jẹ́ kùn láé, àti kò jé ni gáfárà láé.

Ẹyin arákùnrin àti arábìnrin mi, ìdánwò nlá ti ayé yìí ni ìgbọràn. "A ó dán wọn wò ní báyí," ni Olúwa wí, "láti rí i bóyá wọn yíó ṣe gbogbo ohunkóhun tí Olúwa Ọlọ́run wọn yíó palásẹ fún wọn."[10]

Olùgbàlá kéde: "Fún gbogbo àwon tí yíó gba ìbùkún láti ọwọ́ mi yíó ṣe ìbámú pèlú òfin tí a ti yàn fún ìbùkún nã, àti àwọn ètò ibẹ̀, gẹ́gẹ́bí a ti yàn ṣíwájú ìpilẹ̀ṣẹ̀ ayé."[11]

Kò sí àpẹrẹ ìgbọràn nlá tí ó wà ju ti Olùgbàlà wa lọ. Nípa Rẹ̀, Páùlù ṣe àkíyèsí:

"Bí ó ti lẹ̀ jẹ́ Ọmọ, síbẹ̀ ó kọ́ ìgbọràn nípa ohun tí ó jìyà;

"Bí a sì ti sọ ọ́ di pípé, ó wá di orísun ìgbàlá àìnípẹ̀kun fún gbogbo àwọn tí ó ngbọ́ tirẹ̀."[12]

Olúgbàlà ṣe àfihàn ìfẹ́ ìjìnlẹ̀ ti Ọlọ́run nípa gbígbé aye pípé, nípa bíbọ̀wọ̀ fún ìpinnu mímọ́ jùlọ tí ó jẹ́ tirẹ̀. Láé kò jẹ́ rò wípé òun dára ju àwọn ẹlòmíràn lọ. Láé kò jẹ́ wú fún ìgbéraga. Láé kò jẹ́ jẹ́ aláìṣòótọ́. Títí láé nió jẹ́ ẹni ìrẹlẹ̀. Títí láé nió jẹ́ ẹni aṣòótọ́. Títí láé nió jẹ́ ẹni ìgbọràn.

Bíótilẹ̀jẹ́pé a darí Rẹ̀ nípa ti Ẹ̀mí lọ́ sínú aginjù láti dán an wò nípasẹ̀ ọ̀gá ẹ̀tàn, àní èṣù, bíótilẹ̀jẹ́pé ó ti rẹ̀ Ẹ́ láti gbígba àwè fún ogójì ọjọ́ àti ogójì òru àti tí ebí npa á, síbẹ̀ ẹni ibi náà fi àwọn àbá onífanímọ́ra àti tí ndán niwò lọ Jésù, Ó fún wa ní àpẹrẹ ọ̀run ti ìgbọràn nípa kíkọ̀ láti yapa kúrò nínú òhun tí Ó mọ̀ wípé kó tó.[13]

Nígbàtí ìrora ti Getsemani dojú kọ Ọ, níbití Ó ti farada irú ìrora tí ó jẹ́ wípé "ìlàágùn Rẹ̀ dàbí ríro ẹ̀jẹ̀ nlá tí o njábọ́ sílẹ̀,"[14] Ó ṣàpẹrẹ Ọmọ ìgbọràn nípa wíwí, "Bàbá, bí Ìwọ́ bá fẹ́, gba ago yí lọ́wọ́ mi: ṣùgbọ́n ìfẹ́ ti èmi kọ́, bíkòṣe tìrẹ ní kí a ṣe."[15]

Bí Olùgbàlà ṣe kọ́ àwọn ọmọ ẹ̀hìn Rẹ ìṣáájú, bẹ́ẹ̀ni Ó nkọ́ ìrẹ àti èmi: "Ìwọ má a tọ̀ mí lẹ́hìn."[16] Njé à á nfẹ́ láti gbọ́ràn?

Ìmọ́ tí à nwá, àwọn ìdáhùn tí à nfẹ́, àti okun tí a fẹ́ lóní láti dojú kọ àwọn ìpeiníjà tí ayé oníṣòro tí ó nyípadà lè jẹ́ tiwa nígbàtí a bá fí tọkàntọkàn gbọ́ràn sí àwọn àṣẹ Olúwa. Mo tún ṣe àròsọ àwọn ọ̀rọ̀ Olúwa: "Ẹnití ó bá pa àwọn àṣẹ [Ọlọ́run] mọ́ gba òtítọ́ àti ìmọ́lẹ̀, dígbà tí yíó da ológo nínú òtítọ́ àti tí ó mọ ohun gbogbo."[17]

Ó jẹ́ àdúrà ìrẹlẹ̀ mi wípé a ó di alábùkún pẹ̀lú àwọn ọrọ̀ èrè tí a ṣèlérí fún àwọn onígbọràn. Ní orúkọ ti Jésù Krístì, Olúwa àti Olugbàla wa, àmín.

ÀWỌN ÀKỌSÍLẸ̀ RÁNPẸ́

1. "A Wí, Kíni Òtítọ́?" *Hymns,* no. 272.
2. Ẹ̀kọ́ àti Àwọn Májẹ̀mú 93:24, 26–28.
3. Samuẹli Kíní 15:22.
4. Ẹ̀kọ́ àti Àwọn Májẹ̀mú 64:34.
5. Nífãi Kíní 3:7.
6. Gẹnẹsisi 22:12.
7. Gẹnẹsisi 22:18.
8. Joseph F. Smith, "Discourse," *Deseret News,* Oṣù Kọkànlá ọjọ́ kẹ́jìlá, Ọdún 1873, 644.
9. Gordon B. Hinckley, "If Ye Be Willing and Obedient," *Ensign,* Oṣù Kejìlá Ọdún 1971, 125.
10. Abrahamu 3:25.
11. Ẹ̀kọ́ àti Àwọn Májẹ̀mú 132:5.
12. Heberu 5:8–9.
13. Rí Matteu 4:1–11.
14. Luku 22:44
15. Luke 22:42
16. Johannu 21:22.
17. Ẹ̀kọ́ àti Àwọn Májẹ̀mú 93:28.

Àwọn Ìkọni fún Ìgbà Wa

Aó ya àwọn ẹ̀kọ́ tí Oyè Àlùfáà ti Mẹlkisẹ́dẹ́kì àti ti Ẹgbẹ́ Aranilọ́wọ́ tí Ọ̀sọ̀ọ̀sẹ̀ kẹ́rin fún "Àwọn Ìkọni fún Ìgbà Wa." A lè pèsè ẹ̀kọ́ kọ̀ọ̀kan láti àwọn ọ̀rọ̀ kan tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ tí a sọ nínú ìpàdé gbogbogbòò tí ó súnmọ́ jùlọ (rí àwòrán tí ó wà nísàlẹ̀). Àwọn àárẹ̀ èèkàn àti agbègbè lẹ̀ yàn àwọn ọ̀rọ̀ tí ó yẹ kí a lò, tàbí kí wọ́n fi ojúṣe yẹn lé àwọn bíṣọ́pù àti àwọn àárẹ̀ ẹ̀ka lọ́wọ́. Àwọn aṣíwájú ń ṣàtẹnumọ́ iyì ti kí àwọn arákùnrin ti Oyè Àlùfáà ti Mẹlkisẹ́dẹ́kì àti àwọn arábìnrin ti Ẹgbẹ́ Aranilọ́wọ́ máa ṣàṣàrò lórí àwọn ọ̀rọ̀ kannáà ní àwọn Ọ̀sọ̀ọ̀sẹ̀ kannáà.

Àá ń gba àwọn tí wọ́n npéjọ fún àwọn ẹ̀kọ́ ti Ọ̀sọ̀ọ̀sẹ̀-kẹ́rin láti ṣàṣàrò àti láti mú ẹ̀yà ti ìwé ìròhìn ti ìpàdé àpapọ̀ gbogbogbòò tí ó súnmọ́ jù wá sí kílásì.

Àwọn Àbá fún Mímúra fún Ẹ̀kọ́ kan láti Àwọn Ọ̀rọ̀

Gbàdúrà kí Ẹ̀mí Mímọ́ wà pẹ̀lú rẹ bí ó ṣé nṣàṣàrò tí o sì nkọ́ni ní ọ̀rọ̀ (tàbí àwọn ọ̀rọ̀) náà. O lè ní àdánwò láti múra fún ẹ̀kọ́ náà nípa lílo àwọn èlò míràn, ṣùgbọ́n àwọn ọ̀rọ̀ ìpàdé àpapọ̀ ni ìlànà kíkọ́ni lẹ́kọ́ ti a fàṣẹ sí. Ojúṣe rẹ ni láti ran àwọn míràn lọ́wọ́ láti kẹ́kọ́ àti láti gbé ìgbé ayé ti ìhìnrere tí a kọ́ni nínú ìpàdé àpapọ̀ gbogbogbòò ti Ìjọ tí ó súnmọ́ jùlọ.

Se àtúnyẹ̀wò ọ̀rọ̀ (tàbí àwọn ọ̀rọ̀) náà, ní wíwá àwọn ìpinlẹ̀ṣẹ̀ àti àwọn ẹ̀kọ́ tí ó bá àìní àwọn ọmọ ẹgbẹ́ kílásì mu. Bákannáà wá àwọn ìtàn, àwọn atọ́ka tí ìwé mímọ́, àti àwọn ọ̀rọ̀ ti a là sílẹ̀ láti ọ̀rọ̀ (tàbí àwọn ọ̀rọ̀) tí yíó ràn ọ́ lọ́wọ́ láti kọ́ àwọn òtítọ́ yìí.

Ṣe àkọsílẹ̀ ètò bí o ó ṣe kọ́ àwọn ìpinlẹ̀ṣẹ̀ àti àwọn ẹ̀kọ́ náà. Ronú nípa ṣíṣe àfikún àwọn ìbéèrè tí yíó ran àwọn ọmọ ẹgbẹ́ kílásì lọ́wọ́.

- Ṣe àwárí àwọn ìpinlẹ̀ṣẹ̀ àti àwọn ẹ̀kọ́ nínú ọ̀rọ̀ (tàbí àwọn ọ̀rọ̀) náà.
- Ronú nípa ìtunmọ̀ wọn.
- Ṣalábápín òye, àwọn iyè inú, àwọn ìrírí, àti àwọn èrí.
- Lo àwọn ìpinlẹ̀ṣẹ̀ àti àwọn ẹ̀kọ́ wọ̀nyí nínú ayé wọn.

ÀWỌN OṢÙ TÍ À Á Ń KỌ́ ÀWỌN ẸKỌ́	ÀWỌN ÈLÒ ẸKỌ́ TI Ọ̀SẸ̀- KẸ́RIN
Oṣù Kẹ́rin Ọdún 2013–Oṣù Kẹ́wá Ọdún 2013	Àwọn ọ̀rọ̀ tí a sọ ní ìpàdé gbogbogbòò ti Oṣù Kẹ́rin Ọdún 2013*
Oṣù Kẹ́wá Ọdún 2013–Oṣù Kẹ́rin Ọdún 2014	Àwọn ọ̀rọ̀ tí a sọ ní ìpàdé gbogbogbòò ti Oṣù Kẹ́wá Ọdún 2013*

** Fún àwọn ẹ̀kọ́ ti Ọ̀sọ̀ọ̀sẹ̀-kẹ́rin ti Oṣù Kẹ́rin àti Oṣù Kẹ́wá, a lè yan ọ̀rọ̀ (tàbí àwọn ọ̀rọ̀) láti ìpàdé gbogbogbòò ti tẹ́lẹ̀ tàbí ti èyí tí ó súnmọ́ jùlọ. Àwọn ọ̀rọ̀ náà wà ní oniruru èdè conference.lds.org.*

© Ọdún 2013 nípasẹ Intellectual Reserve, Inc. Gbogbo ẹtọ́ ni a fi pamọ́. Tí a tẹ ní USA. Àṣẹ Gẹ́ẹ́sì: 6/12. Àṣẹ Àyípadà èdè: 6/12.
Àyípadà èdè ti *First Presidency Message, May 2013*. Yoruba. 10665 779

Nípaṣẹ Ààrẹ Henry B. Eyring
Olùdámọ̀ràn Kíní Nínú Àjọ Olùdarí Gbogbogbòò

"Wá Sọ́dọ̀ Mi"

Nípaṣẹ àwọn ọ̀rọ̀ Rẹ̀ àti àpẹẹrẹ Rẹ̀, Krístì ti fi bí a ṣe lè súnmọ́ Òhun hàn wá.

Mo ní ìmoore láti wà pẹ̀lú yin nínú ìpàdé àpapọ̀ ti Ìjọ ti Jésù Krístì tí Àwọn Ènìyàn Mímọ́ Ọjọ́ Ìkẹhìn. Èyí ni Ìjọ Rẹ̀. A gba orúkọ Rẹ̀ lé ara wa nígbà tí a bá wọ ìjọba Rẹ̀. Òhun ni Ọlọ́run, Ẹlẹ́dá, àti pípé. A jẹ́ alára ìdíbàjẹ́ ti ikú àti ẹ̀ṣẹ̀ nípá lórí. Síbẹ̀ nínú ìfẹ́ Rẹ̀ fún àwa àti ìdílé wa, Ó pè wá láti súnmọ́ Òhun. Níbí ni àwọn ọ̀rọ̀ Rẹ̀: "Sún mọ́ mi àti Èmi yíó sì sún mọ́ Ọ; wá mi lẹ́sọ̀lẹ́sọ̀ àti ìwọ yíó sì rí me; bèrè, àti ìwọ yíó rí gbà; kàn, àti pé a ó ṣí fún ọ."[1]

Ní àkókò Easter yíí a ní ìrántí nípa ìdí tí a fi fẹ́ràn Rẹ̀ àti ti àwọn ìlérí tí ó ṣe fún àwọn ọmọ ẹ̀hìn Rẹ̀ olóótọ́ láti di àwọn ọ̀rẹ́ àyànfẹ́ Rẹ̀. Olùgbàlà ṣe ìlérí yẹn àti pé Ó sọ fún wa bí, nínú iṣẹ́-ìsìn wa sí I, Òhun ṣe wá sí wa. Àpẹẹrẹ kan wà nínu ìfihàn sí Oliver Cowdery bí ó ti ń sin Olúwa pẹ̀lú Wòlíì Joseph Smith nínú àyípadà èdè ti Ìwé ti Mọ́mọ́nì: "Kíyèsíi, ìwọ ni Oliver, àti pé mo ti sọ fún ọ nítorí àwọn ìfẹ́-inú rẹ; nítorínáà ṣe ìtọ́jú àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí bíi ìtura nínú ọkàn rẹ. Jẹ olóótọ́ àti alápọn ní pípa àwọn àṣẹ Ọlọ́run mọ́, àti pé Èmí yíó ròbà yí ọ ká nínú àwọn apa ìfẹ́ mi."[2]

Mo ní ìrírí ti ayọ̀ ti wíwá sún mọ́ Olùgbàlà áti ti wíwá Rẹ̀ sún mọ́ mi ní ìgbàkúgbà nípa àwọn ìṣe ìrọ̀rùn ti ìgbọ̀ràn sí àwọn àṣẹ.

O ti ní ìru àwọn ìrírí bẹ́ẹ̀. Ó ti lè jẹ́ nígbà tí o yàn láti péjọ fún ìpàdé oúnjẹ Olúwa kan. Ó jẹ́ fún mi ní Ọjọ́ Ìsinmi kan nígba tí èyí kéré gan. Ní àwọn ọjọ́ yẹn a gba oúnjẹ Olúwa nínú ìpàdé ìròlẹ́ kan. Ìrantí ti ọjọ́ kan tí ó ju ọdún márùndínláádọ́rin, nígbà tí mo pa àṣẹ láti kó àwọn ìdílé jọ pẹ̀lú àwọn Ènìyàn Mímọ́ mọ́, yì í n fà mí sún mọ́ Olùgbàlà.

Ìta ṣókùnkùn ó sì tutù. Mo rántí níní ìmọ̀-inú ti ìmọ́lẹ̀ àti líló nínú ilé ìsìn ní ìròlẹ́ yẹn pẹ̀lú àwọn òbí mi. A ṣalábápín nínú oúnjẹ Olúwa, tí a pín nípa àwọn tí ó di Oyè Àlúfáà ti Áárọ́nù mú, ní dídá májẹ̀mú pẹ̀lú Bàbá Ọ̀run wa láti máa rántí Ọmọ Rẹ̀ nígbà gbogbo àti pa àwọn àṣẹ Rẹ̀ mọ́.

Ní ìparí ìpàdé náà, a kọ orin ẹ̀mí "Abide with Me, 'Tis Eventide," pẹ̀lú àwọn ọ̀rọ̀ nínú rẹ̀ "A Olùgbàlà, dúró lálẹ́ yí pẹ̀lú mi."[3]

Mo ní ìmọ̀-inú ti ìfẹ́ àti sísúnmọ́ ti Olùgbàlà lálẹ́ yẹn. Àti pé mo ní ìmọ̀-inú ti ìtùnnú ti Ẹ̀mí Mímọ́.

Mo fẹ́ láti tún tàn lẹ́ẹ́kan si àwọn ìmọ̀-inú ti ìfẹ́ àti sísúnmọ́ Olùgbàlà tí mo ní nínú ìpàdé oúnjẹ Olúwa yẹn nígbà ọ̀dọ́ mi. Ní láìpẹ́ yìí mo pa àṣẹ míràn mọ́. Mo ṣàwárí nínú àwọn ìwé mímọ́. Nínú wọn, mo mọ̀ pé mo tún lè padà láti jẹ́ kí Ẹ̀mí Mímọ́ jẹ́ ki ní ìmọ̀-inú tí àwọn ọmọ ẹ̀hìn méjì ti Olúwa Àjíìnde ti ní nígbà tí Ó gba ìpè láti wá sínú ilé wọn àti láti wà pẹ̀lú wọn.

Mo kà nípa ọjọ́ kẹta lẹ́hìn Ìkànmọ́-àgbélèbú àti ìsìnkú Rẹ̀. Àwọn arábìrin olóótọ́ àti àwọn míràn ri tí a ti yí òkúta kúrò nínú túbú wọ́n sì rí wípé ara Rẹ̀ kò sí níbẹ̀ mọ́. Wọ́n jáde wá nítorí ìfẹ́ Fun láti kun ara Rẹ̀ ní òróró.

Àwọn àngẹ́lì méjì dúró ní tòsí wọ́n sì bèrè ìdí tí wọ́n fi ń bẹ̀rù, wípé:

"È é ṣe tí ẹ̀nyín fi ń wá alààyè láárín àwọn òkú?

"Kò sí níhín, ṣùgbọ́n ó jíìnde: rántí bí ó ti wí fún yín nígbà tí ó wà ní Gálílì,

"Wípé, A kò lè ṣalàìmá fi Ọmọ-ènìyàn lé àwọn ènìyàn ẹlẹ́ṣẹ̀ lọ́wọ́, àti pé a ó sì kàn án mọ́ àgbélèbú, àti pé ní ijọ́ kẹ́ta yíó tún dìde."[4]

Ìhìnrere ti Márkù ṣe àfikún ìtọ́ṣọ́nà náà láti ọwọ́ ìkan nínú àwọn ángẹ́lì náà: "Ṣùgbọ́n ẹ lọ, sọ fún àwọn ọmọ ẹ̀hìn rẹ̀ àti Pétérù wípé ó ṣáájú yín lọ sí Gálílì: níbẹ̀ ní ẹ̀nyin yíó gbé ríi, gẹ́gẹ́bí ó ti wí fún un yín."[5]

Àwọn Àpóstélì àti àwọn ọmọ ẹ̀hìn péjọ pọ̀ ní Jérúsálẹ́mù. Gẹ́gẹ́bí àwa náà ṣe lè wà, ẹ̀rù ń bà wọ́n àti pé wọ́n ní ìyanu bí wọ́n ṣe é nsọ̀rọ̀ papọ̀ nípa oun tí ìkú àti àwọn ìròhìn nípa jí jíìnde Rẹ̀ jẹ́ fún wọn.

Méjì nínú àwọn ọmọ ẹ̀hin náà rìn lọ́sán yẹn láti Jérúsálẹ́mù lórí ọ̀nà sí Ẹ́mmáúsì. Krístì tí a jíìnde yọ ní ọ̀nà náà ó sì rìn pẹ̀lú wọn. Olúwa ti wá sọ́dọ̀ wọn.

Ìwé ti Lúkù gbà wá láyè láti rìn pẹ̀lú wọn:

"Ó sì ṣe, wípé, nígbàtí wọ́n jùmọ̀ sọ̀rọ̀ papọ̀ àti sọ àsoyé, Jésù fún ara rẹ̀

súnmọ́ tòsí, àti pé ó lọ pẹ̀lú wọn.

"Ṣùgbọ́n a dì wọ́n lójú kí wọ́n má ba da mọ́.

"Àti pé ó sì bi wọ́n pé, Ìrú àjọsọ papọ̀ wo ní èyí tí ẹ́ nní ẹnìkan sí ìkejì, bí ẹ tí nrìn, àti tí ẹ banújẹ́?

"Ọ̀kan nínú wọn, tí orúkọ re njẹ́ Kléópà, ní ìdáhùn wí fún un, Njẹ́ àlejo níkan ní ìwọ ní Jérúsálémù, àti tí ìwọ ò sì mọ ohun tí ó ṣe níbẹ̀ ní àwọn ọjọ́ wọ̀nyí?"[6]

Wọ́n sọ Fun nípa ìbànújẹ́ wọn wípé Jésù ti kú nígbà tí wọ́n gbẹ́kẹ̀le pé yí Ó jẹ́ Olùràpadà Ìsráẹ́lì.

Ìníṣẹ́sí láti ti wà nínú ohùn Olúwa Àjíìnde bí ó ṣe bá àwọn ọmọ ẹ̀hìn méjì oníròbìnújẹ́ àti tí nkẹ́dùn:

"Nígbànáà ó wí fún wọn, ẹ̀nyin tí òye kò yé, àti tí ó yigbì ní ọkàn láti gba gbogbo èyítí àwọn wòlîi ti wí gbọ́:

"Kò há à yẹ kí Krístì kí ó jìyà nkan wọ̀nyí, àti kí ó sì wọ inú ògo rẹ̀?

"Àti bẹ̀rẹ̀ láti Mósè àti gbogbo àwọn wòlîi, ó sàsoyé àwọn nkan nípa rẹ̀ nínú gbogbo ìwé mímọ́ fún wọn.[7]

Nígbànáà àkókò kan dé tí ó ti mú ọkàn mi lọ́ wọ́ọ́rọ́ láti ìgbà tí mo ti jẹ́ ọmọkùnrin kékeré:

"Àti pé wọ́n súnmọ́ sí ìletò, níbi tí wọ́n nlọ, àti ó sì ṣe bí ẹnipé yíó lọ́ sí ìwajú.

"Ṣùgbọ́n wọ́n rọ̀ ọ́, wípé, Bá wa dúró: nítorí ó di ọjọ́ alẹ́, àti pé ọjọ́ sì kọjá tán. "Àti pé ó sì wọlé lọ láti bá wọn dúró."[8]

Olùgbàlà gbà, ní alẹ́ yẹn, ìpè láti wọ ilé àwọn ọmọ ẹ̀hìn Rẹ̀ nítòsí ìletò Ẹ́mmáúsì.

Ó jókó ti oúnjẹ pẹ̀lú wọn. Ó mú búrẹ́dì, súre sí i, bù ú, àti pé ó fifún wọn. A ṣí ojú wọn tó jẹ́ pé wọ́n dáa mọ̀. Nígbànáà Ó di òfo mọ́ wọn lójú. Luku ṣe àkọsílẹ̀ fún wa àwọn ìmọ̀-inú ti àwọn ọmọ ẹ̀hìn alábùkún nì: "Àti pé wọ́n sì wí fún ara wọn, ọkàn wa kò há à gbiná nínú wa, nígbàtí ó mbá wa sọ̀rọ̀ ní ọ̀nà, àti nígbàtí ó ntúmọ̀ àwọn ìwé mímọ́ fún wa?"[9]

Ní wákàtí kan náà, àwọn ọmọ ẹ̀hìn méjì náà sáré tete padà sí Jerúsálẹ́hù láti sọ fún àwọn Àpóstélì mọ́kànlá ohun tí ó ṣẹlẹ̀ sí wọn. Ní àkókò yẹn gan, Olùgbàlà tún yọ sí wọn.

Ó ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn àsọtẹ́lẹ̀ nípa iṣẹ́ ìránṣẹ́ Rẹ̀ láti ṣètùtù fún àwọn èṣẹ̀ gbogbo àwọn ọmọ Bàbá Rẹ̀ àti láti já àwọn ìdè ikú.

"Àti ó wí fún wọn pé, Bẹ́ẹ̀ni a ti kọ̀wé rẹ̀, àti pé kí Krístì kí ó jìyà, àti kí ó sì jînde ní ọjọ́ kẹta kúrò nínú òkú:

"Àti kí a wàásù ìròmúpìwàdà àti ìwẹ̀nùmọ́ ẹ̀ṣẹ̀ ní orúkọ rẹ̀ láárín orílẹ̀ ède gbogbo, bẹ̀rẹ̀ láti Jerúsálémù.

"Àti ẹnyìn ni ẹlẹ́rí nkan wọ́nyí."[10]

Àwọn òrọ̀ Olùgbàlà jẹ́ òtítọ́ bákanná fún wa bí wọ́n ṣe wà fún àwọn ọmọ ẹ̀hìn Rẹ̀ nígbà yẹn. A jẹ́ ẹlẹ́rí àwọnnkan wọ̀nyí. Àti ojúṣe ológo tí a gbà nígbàtí a ṣe ìrìbọmi wọ́ inú Ìjọ ti Jésù Jrístì tí àwọn Ènìyàn Mímọ́ Ọjọ́ Ìkẹhìn di kedere fún wa nípasẹ̀ wòlîi Alma ní ọgọ́rún ọdún sẹ́hìn ní àwọn ọmi Mọ́mọ́nì:

"Ó sì ṣe, tí ó wí fún nwọn pé: kíyèsí i, àwọn wọ̀nyí ni omi Mọ́mọ́nì (nítorípé báyí ní à npè nwọn) àti nísisìyí, bí èyin ti ṣe ní ìfẹ́ láti wá sínú agbo Ọlọ́run, kí a sì pè nyín ní ènìyàn rẹ̀, tí ẹ sì ṣetán láti fi ara da ìnira ara nyín, kí wọ́n lè fúyẹ́;

"Bẹ́ẹ̀ni, tí èyin sì ṣetán láti ṣòfò pẹ̀lú àwọn tí nṣòfò; bẹ́ẹ̀ni, àti láti tu àwọn tí ó fẹ́ ìtùnú nínú, àti láti dúró gẹ́gẹ́bí àwọn ẹlẹ́rí Ọlọ́run ní gbogbo ìgbà àti nínú ohun gbogbo àti níbi gbogbo tí èyin lè wà, àní títí dé ojú ikú, kí a lè rà yín padà nípasẹ̀ Ọlọ́run, kí a sì kà yín mọ́ ara àwọn tí ọ́ ní àjînde èkíní, kí èyin kí ó lè ní iyè àìnípẹ̀kun—

"Nísisiyí mo wí fún nyín, tí èyí bá jẹ́ ìfẹ́ ọkàn nyín, kíni èyin ní tí ó jẹ́ ìdènà sí kí a rì nyín bọmi ní orúkọ Olúwa, gẹ́gẹ́bí èrí níwájú rẹ̀ wípé èyin ti bá a dá májẹ̀mú, pé èyin yíò máà sìn in, èyin yíò sì pa àwọn òfin rẹ̀ mọ́, kí Òun kí ó lè da Ẹ̀mí rẹ̀ lé nyín lórí lọ́pọ̀lọpọ̀?

"Àti nísisìyí, nígbàtí àwọn ènìyàn náà ti gbọ́ àwọn òrọ̀ wọ̀nyí, nwọ́n pàtéwọ́ fún ayọ̀, nwọ́n sì kígbe sókè: Èyí ni ìfẹ́ ọkàn wa."[11]

A wà lábẹ́ májẹ̀mú lọ́nà méjì láti gbé àwọn aláìní sóké àti láti jẹ́ àwọn ẹlẹ́rí ti Olùgbàlà níwọ̀n igbà tí a wà láyé.

À á lè ṣe é lâi kùnà níkan tí a bá ní ìmọ̀-inú ìfẹ́ fún Olùgbàlà àti ìfẹ́ Rẹ̀ fún wa. Bí a bá ṣe ṣòótọ́ sí àwọn ìlérí ti a ti ṣe, a ó ní ìmọ̀-inú ti ìfẹ́ wa fún Un. Èyí yíó pọ̀ si nítorí a ó ní ìmọ̀-inú ti agbára Rẹ̀ àti sísúnmọ́ Rẹ̀ sí wa nínú ìṣẹ́-ìsìn wa sí I.

Àárẹ Thomas S. Monson ti rán wa létí lóòrèkóòrè ti ìlérí ti Olúwa sí àwọn ọmọ ẹ̀hìn olóótọ́ Rẹ̀: "Àti ẹnikẹ́ni tí ó bá gbà yín, níbẹ̀ ní Èmí yíó wà bákannáà, nítorí Èmí yíó lọ ṣíwájú ojú yín. "Èmi yíó wà ní ọwọ́ òtún yín àti ní ọwọ́ òsì, àti Ẹ̀mí mi yíó wà nínú àwọn ọkàn yín, àti àwọn ángẹ́lì mi rọ̀gbà yí i yín ká, láti gbé e yín sókè."[12]

Ọ̀nà míràn kan wà tí èmi àti ìrẹ ti ní ìmọ̀-inú sísúnmọ́ Rẹ̀ sí wa. Bí a ṣe é fún Un ní ìsìn tọkàntọkàn, Yíó súnmọ́ àwọn tí a fẹ́ràn nínú ìdílé wa. Ní gbogbo ìgbà tí a ti pè mí nínú ìsìn Olúwa láti ṣí tàbí láti fi ìdílé mi sílẹ̀, mo ti wá ri pé Olúwa nbùkún ìyàwó àti àwọn ọmọ mi. Ó pèsè àwọn ìránṣẹ́ Olólùfẹ́ ti Rẹ̀ àti àwọn ànfàní láti fa ìdílé mi súnmó Òhun.

Ẹ ti ní ìmọ̀-inú irú ìbùkún bẹ́ ẹ̀ nínú ayé yín. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ yín ni ó ní àwọn àyànfé tí wọ́n nṣáko kúrò lọ́na iyè àìnípẹ̀kun. Ẹ má nronú ohun tí ẹ lè tún ṣe láti mú wọn padà. Ẹ lè gbẹ́kẹ̀lé Olúwa láti súnmọ́ wọn bí ẹ ṣe nsìn Í nínú ìgbàgbọ́.

Ẹ rántí ìlérí Olúwa sí Joseph Smith àti Sidney Rigdon nígbà tí wọ́n kò sí lọ́dọ̀ àwọn ìdílé wọn torí ìṣẹ́ Rẹ̀: "Ẹ̀ yin òrẹ́ mi Sidney àti Josefu, àwọn ìdílé yín wà ní dáradára, wọ́n wà ní ọwọ́ mi, àti pé Èmi yíó ṣe pẹ̀lú wọn bí ó ṣe tọ́ sí mi; nítorí nínú mi ni gbogbo agbára wà."[13]

Bí i Alma àti Ọba Mòsíà, àwọn òbí olóótọ́ kan ti sin Olúwa pẹ́ àti ní dáradára síbẹ̀ wọ́n ní àwọn ọmọ tí wọ́n ti ṣáko bíótilẹ̀jẹ́pé àwọn òbí wọn ti rúbọ fún Olúwa. Wọ́n ti ṣe gbogbo ohun tí wọ́n lè ṣe lâi yege, àní pẹ̀lú ìrànlọ́wọ́ àwọn òrẹ́ àyànfẹ́ àti olóótọ́.

Almá àti àwọn ènìyàn mímọ́ ìgbà rẹ̀ gbàdúrà fún ọmọ rẹ̀ àti àwọn ọmọ Ọba Mòsíà. Ángẹ́lì kan wá. Àdúrà yín àti àdúrà àwọn tí ó sa ìgbàgbọ́ wọn yíó mú àwọn ìránṣẹ́ Olúwa wá láti ran àwọn ọmọ ẹgbẹ́ ìdílé yín lọ́wọ́. Wọ́n yíó ràn wọ́n lọ́wọ́ láti yan ọ̀nà ilé lọ sí ọ̀dọ̀ Ọlọ́run, àní bí Sàtánì àti

àwọn atẹ̀lé re bá dojú ìjà kọ wọ́n, ẹnitítí èrò rẹ ní láti rún àwọn ìdílé nínú ayé yí àti nínú ayérayé.

Ẹ rántí àwọn òrò tí ángẹ́lì náà sọ sí Alma Kékeré àti àwọn ọmọkùnrín ti Mòsíà nínú ìwarùnkì wọn: "Àti pẹ̀lú, ángẹ́lì náà sọ wípé: Kíyèsí i, Olúwa ti gbọ́ àdúrà àwọn ènìyàn rẹ, àti àdúrà ìránṣẹ́ rẹ, Álmà, ẹnitítí ì Ṣẹ bàbá rẹ; nítorítí ó ti gbàdúrà pẹ̀lú òpòlọpò ìgbàgbọ́ nípa rẹ, pé kí a mú ọ wá sínú ìmò òtítọ́ nnì; nítorínáà, nítorí ìdí èyí ní èmí wá láti lè fún ọ ní ìdánilójú nípa agbára àti àṣẹ Olórun, kí àdúrà àwọn ìránṣẹ́ rẹ lè jẹ́ gbígbà gẹ́gẹ́bí ìgbàgbọ́ wọn."[14]

Ìlérí mi sí èniyin tí ó ngbàdúra tí ẹ sì í nsin Olúwa kò lé è jẹ́ pé kí ẹ ní gbogbo ìbùkún tí è ẹ́ nfẹ́ fún ara yín àti ìdílé yín. Ṣùgbọ́n mo lè ṣèlérí fún un yín pé Olúgbàlà yíó súnmọ́ yín yíó sì bùkún yín àti ìdílé yín pẹ̀lú ohun tí ó dára jùlọ. Ẹ ó ní ìtùnú ti ìfẹ́ Rẹ̀ àti pé ẹ ó ní ìmò-inú ti ìdáhùn ti sísúnmọ́ Rẹ̀ bí ẹ ṣe n na apá yín síta láti ṣe ìsìn fún àwọn ẹlòmíràn. Bí ẹ ṣé di egbò àwọn tí ó wà ní àìní àti pèsè ìwẹ̀nùmọ́ ti Ètùtù Rẹ̀ fún àwọn tí ó nkẹ́dùn nínú ẹ̀ṣẹ̀, agbára Olúwa yíó mú yín dúró. Àwọn apá Rẹ̀ wà ní níná sítà pẹ̀lú ti yín láti tìlẹ́hìn àti láti bùkún àwọn ọmọ ti Bàbá Òrun wa, pẹ̀lú àwọn tí ó wà nínú ìdílé yín.

Ìpadàsílé ológo wà ní ìpèsèsílẹ̀ fún wa. Nígbà náà a ó rí ìmúṣẹ ilérí ti Olúwa tí a ti fẹ́ràn. Òhun ní yíó kí wa káàbọ̀ sí iyè ayérayé pẹ̀lú Rẹ̀ àti Bàbá Òrun wa. Jésù Krístì ṣà pé júwe rẹ̀ ní ọ̀nà yí:

"Wá láti ṣe àmúwá àti gbígbé kalẹ̀ Síónì mi. Pa àwọn àṣẹ mi mọ́ nínú ohun gbogbo

"Àti pé, tí ó bá pa àwọn àṣẹ mi mọ́ àti pé tí ó forítì dé òpin, ìwọ yíó ní iyè ayérayé, ẹ̀bùn èyí tí ó tóbi jù nínú gbogbo àwọn ẹ̀bùn Olórun."[15]

"Nítorí àwọn tí ó yè yíó jogún ayé, àti àwọn tí ó kú yíó simi láti gbogbo làálàá wọn, àti àwọn iṣẹ́ wọn yíó tẹ̀lé wọn; àti wọn yíó gba àdé nínú àwọn ilé Bàbá mi, èyí tí mo ti pèsè fún wọn."[16]

Mo jẹ́rí pé a lè, nípasẹ Ẹ̀mí náà, tẹ̀lé ìpè ti Bàbá Òrun: "Èyí ni Àyànfẹ́ Ọmọ Mi. Gbọ́ Ọ!"[17]

Nípasẹ àwọn òrò Rẹ̀ àti àpẹrẹ Rẹ̀, Krístì tí fi hàn wá bí a ṣe lè súnmọ́ Òhun. Olúkúlùkù ọmọ Bàbá Òrun tí ó ti yàn láti wòlé nípa ẹnù ọ̀nà ti ìrìbọmi sínú Ìjọ Rẹ̀ yíó ní ànfàní nínú ayé yí láti gba ẹ̀kọ́ ìhìnrere Rè àti láti gbọ́ ìpè Rẹ̀ láti òdò àwọn ìránṣẹ́ Rẹ̀ tí a pè, "Wá sódò mi."[18]

Olúkùlùkù ìránṣẹ́ oní májẹ̀mú Rẹ̀ nínú ìjọba Rẹ̀ lórí ayé àti nínú ayé ti ẹ̀mí yíó gba ìtọ́sọ́nà nípa Ẹ̀mí láti bùkún àti láti sín àwọn ẹlòmíràn fún Un. Àti wọn yíó ní ìmò-inú ti ìfẹ́ Rẹ̀ àti rí ayò ti dídi fífà súnmọ́ Rẹ̀.

Mo jẹ́ ẹlẹ́rí ti Àjíinde ti Olúwa dájúdájú bí ẹnipé mo wa níbẹ̀ ní ìròlẹ́ yẹn pẹ̀lú àwọn ọmọ ẹhìn méjì nínú ilé náà ní ọ̀nà Ẹmmausì. Mo mò pé Ó wà láyé dájúdájú bí Josefu Smith ṣe mò nígbà tí ó rí Bàbá àti Ọmọ nínú ìmólẹ̀ òwúrò dídán kan nínú igbó kékeré ti igi kan ní Palmyra.

Èyí ni Ìjọ ti Jésù Krístì tòtítọ́. Àfi nínú àwọn kọ́kọ́rọ́ ti Àárẹ Thomas S. Monson dìmú ní agbára fún wa láti ṣe èdìdì pẹ̀lú àwọn ìdílé wa láti gbé títí ayérayé pẹ̀lú Bàbá Òrun wa àti Jésù Krístì Olúwa. A ó dúró ní Òjó Ìdájó níwájú Olùgbàlà, ojú kan ojú. Yí ó jẹ́ àkókò ayò fún àwọn tí ó ti súnmọ́ Rẹ̀ nínu ìsìn wọn fún Un nínú ayé yí. Yí ó jẹ́ ayò láti gbọ́ àwọn òrò: "Káàre dáradára, ìwọ ọmọ òdò rere àti olóótọ́."[19] Mo jẹ́rí bẹ̀ẹ̀ gẹ́gẹ́bí i ẹlẹ́rí ti Olùgbàlà Àjíinde àti Olúràpadà wa ní orúkọ ti Jésù Krístì, àmín.

ÀWỌN ÀKỌSÍLẸ̀ RÁNPẸ́

1. Ẹ̀kọ́ àti Àwọn Májẹ̀mú 88:63.
2. Ẹ̀kọ́ àti Àwọn Májẹ̀mú 6:20
3. "Abide with Me; 'Tis Eventide," *Àwọn Orin Mímọ́,* no. 165.
4. Luku 24:5–7.
5. Marky 16:7.
6. Luku 24:15–18.
7. Luku 24:25–27.
8. Luku 24:28–29.
9. Luku 24:32.
10. Luku 24:46–48.
11. Mòsíàh 18:8–11.
12. Ẹ̀kọ́ àti Àwọn Májẹ̀mú 84:88.
13. Ẹ̀kọ́ àti Àwọn Májẹ̀mú 100:1.
14. Mòsíàh 27:14.
15. Ẹ̀kọ́ àti Àwọn Májẹ̀mú 14:6–7.
16. Ẹ̀kọ́ àti Àwọn Májẹ̀mú 59:2
17. Ìtàn—Josefu Smith 1:17.
18. Matteu 11:28.
19. Matteu 25:21.

© Ọdún 2013 nípasẹ Intellectual Reserve, Inc. Gbogbo ẹtọ́ ni a fi pamọ́. Tí a tẹ̀ ní USA. Àṣẹ Gẹ̀ẹ́sì: 6/12. Àṣẹ Àyípadà èdè: 6/12.
Àyípadà èdè ti *Visiting Teaching Message, May 2013*. Yoruba. 10665 779